To the Chief Secretary to the Government

# EKO AKETE.

"EMI YIO FI OHUN 'TI O NDUN MAKUNNU HAN AWON ALAGBARA, NGO SI JE ALAGBAWI AWON ODI."—W. T. STEAD

VOL. V. NO. 259 SATURDAY, JANUARY 28 1928. 4d.

The Leading Weekly Vernacular Newspaper in Nigeria.

NIG... SECRETARIAT -1 FEB. 1928



## White's Radical Gonkiller.

:o:

(NATIVE.)

[ *A complete cure for old and fresh Gonorrhoca.* ]

When Gonorrhea is not properly cured, it gives rise to other troubles and diseases, such as Barreness, Piles, Kidney Diseases, Stricture, Rupture, Rheumatism, Sore-eyes, etc.

N.B.—This Medicine cures Gonorrhea completely in either man or woman, so that no secondary diseases can follow.

Made from pure **Native Herbs,** and sold only by

VICTOR WHITE, ESQ., *Chemist.*

41, Offin Road, Lagos.

PRICE: **Ten Shillings (10/-)** per bottle.

*Packing and Postage 2/6d. extra, to all parts of Nigeria.*

EGBOGI ALAWOTAN ATỌSI.

:o:

[ *Fun Atọsi lailai ati titun.* ]

Ti a ko ba tete wo Atọsi san daradara, o ma ndi enia lọwọ lati ṣe abiamọ, o si ma nfa origi arun mi wa, bi:—Jẹdi-jẹdi, Aran, Iju, Ẹda, Ipake, Ase, Lakuregbe, Arun Oju, ati arun mi.

*N.B.*—Egbogi yi nwo Atọsi san lawotan patapata, ko si njẹ ki o ri aye wu arun mi silẹ.



A. Glen ... Secretariat ...

"AWA O MA JO, AWA O MA YỌ, NI"

Aga ati Asia (*Flags*) ti Germany lorișirișì wa fun hihaya ni No. 3, Docemo Street, Lagos. Aga ati Asia wọnyi dara fun akękęyęyę pupọ, fun Igbeyawo Wolimọ, Ijọ-Ọdun Musulumi, tabi ti Kiriyo, fun ere nile Ẹgbẹ, ati orișirișì ohun ayọ miran.

*Terms very moderate*

for particulars, please apply at :—

EKO-ATORO CHAIRS & FLAGS SUPPLY

*Office* :—

No. 3, Docemo Street,
P.O. Box No. 505.
Lagos, Nigeria.

**Coffins to suit your Taste.**

Coffins with Pillows, Shroud, Brass Edges, and Removable Lids, on sale at J. B. da Silva, 40, Odunlami Street, Lagos: also Gramophone Records, Gas-lamps, etc., etc.

Prices to suit you. No worry, prompt attendance. Make a call.

## Ero ya wa ra

ADEBOYE ȘOLANKẸ Onișowo "Gbabiọgẹdẹ" nta Panu-kikọle ati kikan-okọ, Iṣo lorișirișì, Kọkọrọ (Ișika) t'ilẹkun ati t'apoti lorișirișì, Atupa fifalọwọ, Simẹnti, Ọda lorișirișì ati Epo-oda, Fikifiki, Okun ẹrọ, ati Ọșan, ati Pakun ti Awo-ẹja lorișirișì, Awo ti awọn Aganyin fi nko Ẹja-șawa Pokun ati Ẹja Abọmafọ, ni Șọbu rẹ ni No. 4, Idunmagbo Street, (l'ebute Olowu) ati ni No. 19, Moloney Bridge Street, (l'Anikantamọ) l'Eko.

**O nta Iworo (Golu) ati Fadaka-tutu ati Irin-iṣẹ Agbẹdẹ Iworo ati Fadaka.**

**Owo Ọja rẹ fanimora. Ẹ lọ ra tiyin nibẹ.**

**Are you a Mechanic ?**—If so you must want Tools, now or soon!

**Do you intend to put up a house ?**—Then you will require Builder's Hardware!

In either case you cannot do better than call at

### B. C. Vaughan's "Excelsior" Stores

at Agarawu Street, Lagos.

Where the largest and most varied assortment of Artisan's Tools and Building Materials in Lagos is stocked.

Quality to satisfy all demands, and prices to suit all pockets.

*Special discount to Traders and Wholesale buyers.*

### J. C. VAUGHAN

Ti ile-ọja Sheffield ni ita Kakawa ati ile-ọja *Excelsior* ni ita Agarawu ni orișirișì ati oniruru ohun kikọ 'le fun tita ni owo-ọpọku-ọyọku.

Ilẹkun awọn ile-owo mejeji wọnyi și silẹ fun awọn Ọmọle ati awọn Gbẹnagbẹna : bi o fẹ da awo ni o, ero-ija dida'wo ko ni jẹ ọ ni'ya lati ra nibẹ :

Alagbẹdẹ Wura tabi ti Fadaka ni ọ ni o, gẹgẹ l'oșe fun ọ lati re yan irin-iṣẹ tirẹ nibẹ ba kanna.

Owo Ọgbẹni J. C. Vaughan ti di Owo Atari-Ajanaku lọjọ to ti pẹ : bi Ọgẹdẹ si ni Owo rẹ ngba kakiri ibikibi. Agbẹ ni ọ kai ! bi o ri orișirișì Ọkọ ti o ri ra nibẹ ha yio șe o.

Sure tete iwọ Ọmọle, iwọ Gbẹnagbẹna, iwọ Aranbata, iwọ Asenjẹ iwọ Ageginigbo (*Sawyer*) Alagbẹdẹ Wura, iwọ Alagbẹdẹ Fadaka, iwọ Agbẹre ba ori're tirẹ pade nibẹ.

Owo-lọwọ ni gbogbo ọja meremere jibẹ.

*Editor & Proprietor :—*
ADEOYE DENIGA,
*Office 24,* Williams Street,
Lagos, Nigeria.

**ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.**

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹta | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*

## GBOHUN-GBOHUN.

### A GBE YEYE, OJONTO!

A gbọ pe ọkọnrin kan ti o ni on njẹ Akitoye Baba pẹlu awọn wonpari bi meji kan fi ipa gbe obinrin kan ni ojonto lọ si ibi kan ni lọlọyi, nwọn si hũ ni iwa ti ko wọ, ẹjọ na ti de Kotu Ọlọpa, a si gbọ pe Kotu awọn *Jury* ni asọtan ẹjọ na yio sọle si.

### MUNISIBA, Ẹ ṢEUN ṢEUN.

Gbogbo awọn to nlọ ra nkan l'ọja Ita Faji, ni nwọn sọ ti aye ti o wa fun olukuluku enia lati rin lọ s'oke s'odo larin awọn alata oniyọ lalai si fifun kan, iru eyiti o ti wa ri tobẹ ti a fi sọ pe aye ki fẹrẹ si rara fun awọn ero igbọnre: eto ti awọn Munisiba si to awọn obinrin alata oniyọ l'ọja na ni ọsẹ yi jẹ eyiti ẹnikẹni ti o lọ sibẹ sọ pe o dara gidigidi tun ẹniti o nta ati ẹniti o si nra pẹlu.

### B' O DURO, O R' ENMỌ!

Irufẹ fere ti awamọto kan fọn ni *Tuesday* yi leyi nigbati o nja lọ ṣõro niwọn agogo mẹrin ọjọ na si ọna oko: nigbati a si rõ itumọ ede yi a ri pe otitọ sãn ni: talo le duro de mọto ti o njabọ bi Ajanaku ti ina ogun jo lalai r' enmọ; ki Baba ṣọ ni.

### A DUPẸ DUPẸ.

A dupẹ lọwọ Ile-owo Dada Adeṣigbin & Sons fun Iwe Ikajọ ọdun ti nwọn ti fun ni loṣu yi, bẹ si ni a ṣọpẹ sọpẹ lọwọ Ọga Ile Ẹrọ Itẹwe "Tika-Tore" ati Ọgbẹni Olugbile Oniṣowo fun Ikajọ oṣu ọdun ti nwọn fi jin ni loṣu yi bakanna.

## IṢẸ WO NI A NI ṢE.?

**Lati ọwọ Kekere- Awo.**

Si Oniwe-irohin "Eko Akete,"

Mo bẹrẹ foji o,

Iṣẹ wo ni a ni iṣe, eyiyi ni ibere pataki ti a ni lati bi arawa lere, iṣẹ mẹta pataki li a ni iṣe lọsẹ yi, iṣẹ mẹtẹta na, ekini nipa ọran owo, ( *Trade's affair* ) ekeji nipa Ajakalẹ arun ekute ( *Bubonic Plague* ) ẹkẹta ni ọran ewu Mọto ( *Motor accident*) larin ilu wa.

Ohun mẹta pataki yi lo nda ilu wa lamu nisisiyi, eyiti a le fi ogun rẹ gbari wipe iṣẹ ti Ọlọrun fẹ wa fun ni, nitoripe kosi ohun ti o ṣẹhin Rẹ lori ohun gbogbo ti ẹda ba nri yala wahala tabi alafia, yala ẹkun tabi ayọ; eyiti a ba fi ṣe ẹkẹrin ọran wa ni ọran owo-asingba ti o fi dugbedingbe lori ilu wa, ṣugbọn eyi dabi ẹkun ti o ba ikun wa, nitoripe a nke fun awọn Ijọba wipe owo yi ki iṣe ohun ti yio fun ilu ni alafia arara, ṣugbọn Ijọba koi ti kuta gbogbo irufẹ aroye bawọnni, lai tilẹ ti bẹrẹsi gba owo na ọpọlọpọ awọn enia ti ku si ogurodo silẹ di aseko ti Ijọba nso wipe awọn yio bẹrẹsi owo na ni gbigba, kilo mu eyiti a wi yi wa, ki iṣe wipe a nfẹ fi fun ara wa ni ominira rara, ṣugbọn olukuluku wa nwo owo ti on ni lati fi ṣe ọmọ enia ti on ni lati fi ṣe fuja bi on ti fẹ ani olukuluku wa nwo bi on tiṣe ṣe wahala si ki on to ri iba elo ti o mbẹ ni ọwọ ni ipamọ yala ninu yara tabi ni Bangi ti Ijọba si ni lati yo elo kan kuro nibẹ lasanlasan lẹhin igbati oluwarẹ ba ti ṣe akọnta oniruru bukata ti on nfi owo ṣe tan, ani lẹhin igbati oluwarẹ ko ba Ijọba dowo pọ ti oluwarẹ si ni lati ma da esu adaiko, tabi ti o ni lati ma yan Saka fun Ijọba lọdọdun.

Lori eyi ti a nsọro le lori wipe o tun nfẹ nkun idamu ti o mbẹ larin ilu Eko yi loni, ṣugbọn a ko ba ti ọran owo-asingba ( *Income Tax* ) wa lọsẹ yi.

A ti sọ ọpọlọpọ ọrọ sinu iwe nipa ọran owo yi, awọn ẹlomiran sọ ti ede oyinbo titi, awa na sọ ti ede Yoruba titi ẹnu wa fẹrẹ bo, sibẹsibẹ Ijọba ṣe eti kunkun wipe ẹnu wa ko lo dun si ọrọ iyẹn? Mo bere ni, boya lọsẹ to mbọ bi iṣẹ ti a ba ni iṣe ko ba to nkan, a le ṣe ṣawura lati fi gbogbo wosika wa ṣe ti ọran owo yi lẹkansi lọsẹ to mbọ

a fẹ şişẹ diẹ lori ọran mẹta ti a wi şaju, laisi tabi-tabi ominu ni awọn ọran na nkọ wa.

IGBA GBO !

Ninu ipari wosika wa ninu iwe'rohin yi ti ọjọ 10 oşu December to lọ yi, bi a ti bẹrẹ labari yi, aye si fun wa diẹ nigbana ni ko jẹki a le pari rẹ, lẹhin eyi ọpọlọpọ işẹ miran ti a tun nmu şe lati igba na tun jẹ ohun idina fun wa lati pari labari na.

Nibiti a gbe sọrọ de ni wipe awọn enia dudu ti o mbẹ larin ilẹ yi iwa arankan ani iwa tẹmbẹlẹkun ati inunibini lo ndamu wọn ni ko jẹ ki nwọn le ri anfani ara wọn jẹ gẹgẹbi awọn oyinbo ti nfẹ anfani arawọn lọpọlọpọ lati ipilẹşẹ ani lati irandiran wọn.

Awọn oyinbo nwọn so ọwọ pọ, nwọn mu ara wọn ni ọmọ iya kanna nwọn nda owo pọ, ti ọdun ba pari nwọn a şe akọnta gbogbo işẹ ti nwọn ti nşe, bọ lati oşu kejila, nwọn a mọ iyatọ ere tabi adanu ti awọn ra lori işẹ wọn, bi nwọn ba ri ọpọlọpọ ere nwọn a fi si ipamọ, nwon a tun ma ba işẹ wọn lọ, bayi ni nwọn tişe njẹ anfani arawọn.

Gbogbo awọn oyinbo onişowo ti a nri ni ilẹ yi lati ilu wọn ni nwọn ti mu owo wa, ki işe igbati awọn wa npade arawọn ni ilẹ yi ni nwọn nda owo şişe silẹ, ẹnikan ni nwọn fi şe olori tabi Alabojuto owo, ki işe orukọ gbogbo wọn ni nwọn njẹ fi şọwo, wipe nitoripe gbogbo wa li a jumọ da owo silẹ, nitorina, gbogbo wa ni a ni lati fi orukọ wa si ode, agbẹdọ ko ri bẹ, ki isi işe boya ẹnikan lo jẹ pataki, nitorina li a tişe ni lati lo orukọ rẹ fun owo ko ri bẹ arara, ẹniti o ba wu wọn ni nwọn ma mu, inu gbogbo wọn yio si dun si i, bo ba şe wipe awọn enia dudu ni ko ni lori ko ni nidi, ẹnikan yio ma jijadu wipe oruko mi ni ki nwọn ma fi şe owo, nipa eyi, ojantuko ti oro ni nwọn ma fi şe, irufẹ iwa arankan bayi ni awọn oyinbo ko ni lọwọ, ti gbogbo ohun ti nwọn nşe fi nşe won lanfani ani ti nwọn fi njẹ anfani arawọn loni.

Nitotọ awọn oyinbo onişowo, ẹnikan şoşo le da owo rẹ silẹ ki arọmodọmọ rẹ ma gun ori owo na, bi owo na ko ba lọ tara, eyi ko ni ki nwọn maşe sọ di ti ẹgbẹ ki o si tun ma lọ bakanna bi atẹhinwa, omiran si mbẹ ninu wọn ti Ọlọrun ba fun ni asiki o le ya owo tirẹ ki on nikan si ma da nkan rẹ şe iyẹn ki işe ija.

Ẹnikan şoşo si le ma da owo şe fun ararẹ ki o ma fi oruko pe ararẹ rẹ ni ẹgbẹ bayi pe So-So-and So Coy ; tabi & Son ; tabi Limited ; ti o ba si ri wipe ajeje ọwọ kan ko gbe ẹru dori tabi agbajọ ọwọ li a fi nsọ iya, o le gbe iwe sode wipe ki awọn ẹlomiran wa ba on sowọ pọ, ti ko si ni bikita pe dukiya ti on nikan lo pọju nibẹ, ti o si jẹ wipe bi nwọn ba ri ere lori owo na, ẹnikan ko ni ko ere ju ẹnikan lọ, awọn ẹniti o ba ti de ilu oyinbo ri, bi awa ti a nsọrọ yi ko tilẹ de okun Ankara debi okun Saro ri, ti oju oluwarẹ ba ranlẹ si ohun daradara, ki işe awọn ẹlomiran ti o jẹ wipe nwọn le de ilu oyinbo tan ti inawo rẹpẹtẹ ọhun ko ni le jẹki nwọn duro şe ọsẹ meji nibẹ li a nwi, nwọn le jẹri si ọrọ ti a nsọ yi.

Kosi ibiti awọn oyinbo le ri arawọn ti nwọn ko ni mu arawọn gẹgẹbi ọmọ iya kanna, koda ki omiran pada kuşẹ to ekute Şọşi, nwọn ko jẹ fi oju foda wipe tani nşe ẹgbẹ eleyi gẹgẹbi aşa awọn enia dudu, eyiti o jẹ wipe bi omirran ba tilẹ jaja tiraka de ilu Gambia nitosi yi lai tilẹ ti de okun Liverpool debi England tabi London nibiti nwọn gbe nlọ kọ işẹ Lọya tabi Dokita, kosi ẹniti o tun to gba laiye yi mọ, tabi ki ẹlomiran jaja di Lọya tabi ki o gba oye Ọlọrun toto, o gbọdọ duro si iwaju rẹ debi ti o ma ni o nfẹ ba sọrọ, ni iwọn igbati oluwarẹ ko gbe işẹ lo fun wọn şe, ki nwọn ma fi gbe oluwarẹ sọnu bi igbati a fi ẹsẹ gba Football gbogbo irufẹ moso-mobo bawọnni ni ko si fun awọn enia funfun ti nwọn si fi nşe arawọn lanfani loni. Ki a ti ibi eyi wo, nigbati Ajakalẹ-arun Ekute nja pupọ larin ile, Ọkọ kan ko ni ti ilu oyinbo de, ki awọn ogunlọgọ oyinbo maşe ba de bi nwọn ba si de bẹ nyẹn ki o to şẹju pẹ nwọn ti wo işẹ ni *Municipal* fun Arun Ekute yi tabi bi iru işẹ omiran, nwọn nwa ijẹ fun ara wọn, eyi fihan gbangba wipe ifẹ ti awọn oyinbo ni si arawọn, ti Ọlọrun lo ya iku, enia dudu ko le ni irufẹ rẹ lailai nibo, nibiti nwọn a ma kọ arawọn wipe ẹnikan ko gbọdọ de ọdọ lagbaja tabi lamurin ni nwọn ti ma roju eyi, Ọlọrun ma jẹ lailai.

Işẹ ti oyinbo mẹta le şe nwọn a gbe fun enia dudu kan lati şe, nibiti o tẹ ki oyinbo meji wa oyinbo mẹjọ lo ma ba nibẹ eyiti awọn mẹfa iyoku i ba şe awọn enia dudu ni wọn ma gbe le lọwọ lati şe, o ka dẹ ni ti nwọn ba şe bayi nkọ owo ti nwọn ni lati san fun awọn oyinbo ti o yẹ lati wa nipo awọn enia dudu mẹfa ni nwọn ma san fun wọn, irọ funfun patapata, ọpa bi owo awọn oyinbo meji pere ko ni ju ti awọn enia dudu mẹfa lọ, iwọ ma gba a, şe ti ko ba rọ ẹ lọrun, o le ba ẹsẹ rẹ sọrọ, bi iwọ tilẹ ni iwọ ko le şe e, awọn ẹniti o ma gba ipo rẹ ti duro ti ẹ ni'pokọ gba-gba-gba, a ko fi eyi da awọn oyinbo lẹbi arara, a nsọ gẹgẹbi ifẹ ati isowọpọ ti awọn oyinbo ni si arawọn ni.

Awọn enia dudu nwọn ko mọ ohun ti nwọn nşe, iwa aigbọran lo si nda wọn lamu, o ni iye igba ti nwọn ma nba arawọn sọ irufẹ ohun ti a nsọ yi sinu iwe, şugbọn ti iwa aigbọran ani iwa aja ti o ma sọnu ti ki igbọ ofe, ko jẹki nwọn le sun pẹtẹ ki nwọn ro ori arawọn ro.

Awọn ẹniti ọrọ ti a nwi yi ye ko wọpọ awọn ẹniti o si le şe gẹgẹbi eto ti awọn oyinbo ni, nwọn ti fi iwa arankan ati iwa ọtẹ yi ara wọn lori, on lo si ntọ wọn ati awọn ọmọ wọn loju la loni.

Bi ko ba jẹ bẹ ogunlọgọ ọmọ ilẹ yi loni, nwọn a ma rin igbanraye kiri ilu pe awọn nwa iṣẹ ti awọn yio ṣe ti omiran fẹrẹ wa iṣẹ to ọdun gbọrọ ki o to ri iṣẹ ọlọgbọn ṣile ṣe.

Bi nwọn ba pa awọn iwa bọrọkọ wọnyi ti, ti nwọn ba mu arawọn Ọkan gẹgẹbi ipo ti olukuluku wọn wa, ki nwọn ma ṣe gẹgẹbi eto awọn oyinbo ko ni jẹ itẹlọrun fun wọn ati irandiran wọn, nwọn ha le ṣe bayi bi? Ijadu emi lo wa nibẹ emi ni Ajirọba, emi ni ọmọloju oyinbo bi oyinbo ko ri mi ko ni ṣe nkan, kọ ni nwọn nbaja kiri.

Awọn oyinbo npe wọn ni Lagido nwọn npe arawọn ni Erin, eyiti awa ri wipe kosi ohun anfani kan nibẹ ju wahala ile aiye lasanlasan lọ.

Bi a ti nni kosi-kosi yi, ọmọ onilẹ ntẹ jẹjẹ ajeji ntẹ girigiri, ara oke ti o ba ẹ ni ilẹ yi ti ra ẹṣin, bi awọn ara ile wa ba fẹ ṣe fuja wipe awọn nra Mọto bi nwọn koi ti mu ohun iduro bi Ganrandi ile lọ si Ẹhingbẹti nwọn ko le ri Mọto ra awọn Ajeji nwọn a ra Mọto fa bi nwọn ti fẹ ko ni ni wọn lara, nwọn ko tilẹ ni mọ wipe nibi kan ni awọn ti mu owo lọ fi ra Mọto, ṣugbọn iwọ wa nibẹ iṣẹ rẹ ko ju iṣẹ keta ati iṣẹ tẹmbẹlẹkun tabi iṣẹ mo-ju-wọn-lọ lọ.

Igba gbo fun olukuluku nisisiyi gbogbo awọn ẹniti owo ti nwọ ile fuv fa ti nwọn nnu ti nwon nyọ bi ekolo abata di ẹniti o tun ki ori si ile bi Abawun Ajapa, nigbati owo mbẹ lọwọ olukaluku anfani ni nwọn fi ṣe fun ara wọn?

Pẹlu bi a ti ni gbogbo igba yi di bi o ti da yi, bi awọn enia dudu ba jagbọn tabi ti nwọn ti nwọn ti gba ọrọ si arawọn lẹnu ti nwọn ti so ọwọ wọn pọ bi awọn oyinbo ti mu arawọn ni ọmọ-iya, o da mi loju wipe ko le ri bayi.

Ki iṣẹ wipe bakanna ni igba ma nlọ fun awọn oyinbo papa, nigbamiran, omiran le ṣubu lori owo ki o ma si le dide mọ, ṣugbọn bi o tiwu ki o ri ko ni iṣe gbogbo nwọn ni yio kuku ma ṣubu si owo kanna, a ko gbọ bayi a ko si ri bayi ri, bi awọn kan tilẹ nṣubu lori owo, ao tun ma ri awọn omiran ti yio tun ma dide, bẹ ni gbogbo nkan ma nlọ si.

O dara pupọ bi ẹ ba le ṣe ironupiwada nitori aseko na koi koja ju, kosi ire kan ti ọtẹ ṣiṣe tabi iwa arankan le ṣe fun ni bikoṣe abamọ; a tọrọ irẹpọ fun iran enia dudu, ki Ọlọrun jẹki nwọn gbọ ki nwọn gba, lọjọ omiran ọjọ're, nko fi imọran kekere kan han lọna ti nwọn yio mu gba, a ṣi duro nihin na.

## AJAKALẸ ARUN EKUTE ATI MUNISIBA.

Ọpọlọpọ wa loni lo mọ riri iṣẹ ribiribi ti awọn Alabojuto ilera ilu labẹ Munisiba ti nṣe lati ọdun keta ti Arun Ekute ti nja ni aria ilẹ yi ati kakiri Igbereko rẹ.

Arun yi bẹrẹ ninu ọdun 1924 o ja pupọ nigbana tobẹ ti ominu fi nkọ ilu, nigbati o si tun di ninu ọdun 1926, o tun ja bakanna, ti ọdun 1925 ko le to ti inu awọn ọdun meji ti a wi loju wa, ki a ṣaṣa kuku sọ wipe lati inu ọdun 1924 yi titi ọdun titun ti a bọ si, Arun yi koi ti dẹkun jija, gẹgẹbi irohin rẹ ti awọn onilu nfi sinu iwe irohin.

Lati igba yi ni awọn Ijọba ti jẹki awọn Alabojuto ilera-ilu mura si ṣiṣẹ pataki lati le pa ina Arun yi mọ́, eyiti a nri irufẹ inawo ribiribi ti awọn Ijọba nṣe si idi ọran yi, ti awọn ara ilu papa si nṣe akatakiti le lori lati le fi ki arun na wọ nipa pipa awọn Ekute ile wọn, ati nipa gbigbadura si Ọlọrun pẹlu pe ki o dawọ Arun na duro.

Ni lọlọyi a tun ngbọ okiki arun yi pe o tu nja labẹbẹ firifiri bẹni awọn Alabojuto ilu si tẹ ṣokoto bọ wipe ọmọ ti o ni ki iya on ma sun on na ko ni fi oju ba orun, nipa eyi a ni lati ki awọn Ijọba ku iṣẹ a si tun ni lati yin wọn gidigidi fun inawo rẹpẹtẹ ti nwọn nṣe fun ti arun na.

Ṣugbọn nwọn a ma pa owe kan bayi pe "Ajọwọ ohun ti a ba jọ wo" lo ngun, owe na lọ bayi pe lọjọ kan, ogun nfẹ lọ wo nkan lọrun, o ya o pe aọwn Irunmọlẹ mẹrin pe ki nwọn ba on ka lọ wo nkan na, nwọn ṣe nwọn fi ori le ọrun, nigbati nwọn de ọhun nwọn ti tẹ ẹni kan silẹ de ogun lati joko si i, ki nwọn to tẹ ẹni yi silẹ de ogun, nwọn gbẹ koto kan silẹ ti o jin daradara lori koto na ni nwọn tẹ ẹni si, bi nwọn ti ni ki ogun lọ joko si ori ẹni, bẹni awọn Irunmọlẹ ẹgbẹ rẹ daro si'rawọn lẹsẹkanna nwọn si ko lati joko si ori ẹni yi, i ba ṣe wipe nwọn ko jumọ lọ ni, ogun iba joko si ori ẹni na i ba si jin si ọfin, nipa eyi ni nwọn fi ma npa owe yi wipe "Ajọwo ohun a ba jọ wo lo ngun" itumọ owe yi ni pe ohun ti a ba jumọ ṣe lo ndara, o dabi ẹnipe awọn Alabojuto ilu ti nwọn nba Arun-Ekute jagun ko fẹ fi ti awọn ara ilu mu ọna ti nwọn tun ngba nipa arun yi mọ, awa si ro wipe eyi ku diẹ ki a to ni iwọn igbati o jẹ wipe wahala nla ni Ijọba nṣe si idi arun yi ẹwẹ ti o si jẹ wipe ogidileje owo ni nwọn nna si i.

Bi nwọn ba fẹ mu ni ọna ti o tọ gẹgẹbi inawo ti nwọn nṣe, i ba dara ki nwọn pe awon ara ilu, ki nwọn pe awọn Ṣọṣi ki nwọn pe Mọṣalaṣi, ki nwọn pe awọn Babalawo, ki Ijọba ba wọn sọrọ lati jiroro le arun yi lori ni ohun ti nwọn yio ṣe ti Ọlọrun yio si bun wọn ni iṣẹgun lori arun Ekute yi, ọna ti nwọn ba ma gba nibẹ ki nwọn mọ ọ

Lẹhinna irufẹ ile ti nwọn nfiu, ki nwọn jẹki olukulnku awọn ara ilu ma wa gba ohun ti nwọn yio ma lo sinu wọn eyi dara julọ loju wa, ki Ijọba ma fi ṣe wipe ṣe awọn li awọn nnawo nkan wọn sibẹsibẹ ko di eyiti awọn onitọju ilu nṣe lọwọ, yio tubọ fi dara ni,

Ero ti wipe ki a ma jẹki awọn ara ilu ma palẹ gbogbo ile wọn mọ si ode lati ma fin ile, o dabi tuna-aṣiri epe male, bi a ba fun awọn ara ilu laṣẹ pe nkan bayi ni ki ẹ ma wa gba ki ẹ ma lọ sinu ile nyin lẹhin ti ẹ ba ti ngba ile nyin ti o nmọ ton-

toni tan, lẹhin na ki Ijọba si jẹki awọn Alabojuto ilu ma fun aw n ile kankan bi Takute mẹrin-mẹrin lati ma lo fun E ute fun bi oṣu kankan ki nwọn to ma wa ko, i ba dara dieju bayi lo, ijaya wipe awọn Mmisiba mbo wa fi ile papa le mu ẹlomiran di alaisan ki o si fi ibẹ gba lọ.

Ti eyiti a nwi yi ba le ri bẹ yio dara julọ gidi-gidi, imọran li eyi a ko fi paṣẹ.

EWU-MỌTO LARIN ILU.

Nigbati a gbe awojiji ti a fi wo gẹgebi ọran ewu Mọto ti nl si ni arin ilẹ yi ati kakiri igbereko nihin loni mu wa mbẹ ni mu.fu-ẹdọfiu.

Ọran yi o nso ogbọn kọ, o so were kọ, o di chun iṣoro g digidi.

Nigbamiran Mọto le ṣeṣi kọ lu enia ki Oluwarẹ si fi ara pa lasan, tal i ki o ti ibẹ yọ si run, n obamiran ẹwẹ awọn " omọ-ọiẹka " ti nwọn nwa Mọto le wa Mọto ni iwakuwa ti yio fi lọ pa ṣe enia j mbi, bakan meji ni nitori ẹniti ko ba mọ idasi ọran yi, o le ti ibẹ ṣẹ Ọlọrun.

Moto ba k lu ẹni'an tabi ti o ṣe ẹnikan ni jamba ti nwọn si ra Dẹrẹba Mọto na mu ti o dogun ile ẹjọ tabi Az z ze ti nwọn ba ro ẹjọ rẹ tan bi o tiṣe fi Mọto ṣe jam a aw n Juri vio ṣe ṣ iwi ri le lori, lori ṣawura awọn Juri ni onidajọ yio ṣe idajọ si, nigbati nwọn ba si daiọ ẹwọn gbọrọ fun om ran, anu ọmọ enia yio ṣe enia.

Ṣugbọn sibẹsibẹ awọn Dẹrẹba wonyi ba ṣe ironupiwada bi ? Nibiti awọn ẹlomiran yio ma ṣe inufuru ẹdofiaru ti y o ma gbadura nigbagbogbo pe Ọlọrun ma jẹki on ri ijangban ninu iṣẹ na, nibẹ ni awọn ọmọ ojẹka mirar. yio ma sọ wipe ki si kuku ki lo m i da irulẹ awọn ẹni bẹ ni ko yẹ lati anu tun ni ig ati ẹwẹ ba sọ wọn, eyiyi ni pe nigbati nwọn ba dajọ ẹwọn tabi pipa fun omiran ninu wọn.

Gẹgẹbi o ti jẹ wipe a koi fẹ iru awon jamba ti Mọto nṣe fun enia ku yi, yio dara julọ bi Ijọba ba le ṣe Ṣawura le lori lati lo fun ọna yi.

A ri lọjọ Satide ijẹjọ wipe awọn Olori ọlọpa (*Commissioner of Police*) ti yi ọna Mọto to nko ero lo si Ebute Mẹta pada si Broad Street, lati ibẹ si Balogun Street titi gba Ereko Street lo gba Ebute Ero lo gun ori kereni fun lilo si Ebute Mẹta, ati eyiti o a nbọ lati Ebute Mẹta nikan ni yio ma gba Victoria Street wa si Tinubu.

A ngbọ wipe lati fi ṣe idena ewu m to li eyi, ẹwẹ a si tun ngbọ wipe nipa titun ọna ṣe ni Victoria Street ni sababi rẹ, eyikeyi o wu ti o le jẹ nibẹ, o dara ki Ijọba ṣe ṣawura pataki n pa rẹ ninu ọdun yi.

Emi ni tiyin nitotọ,

KEKERE AWO.

## News from Abeokuta.

### A JOYOUS WEDDING AT ABẸOKUTA.

1. The marriage between Mr. Isaac Babatunde-Ṣotoluwẹ and Miss Janet Olatunde Sowande a dughter of our celebrated po t of Ẹgba Land Mr. Sobo Ṣowande whose bard c appelation commonly known throughout Yoruba land as Sobo Arobiodu—a brother to the late Revd E. J. Ṣowande, of the Christ Church Lagos, D. O. Ṣowande, Esqr, the famous President of the native Court Ake Grade A., Mr. S. G. Ṣowande the Headprinter of the Ẹgba Native administration where the Bride room has been working arduously as one of the staff of the Printing Department for the past twelve years was solemnised at Christ Chnrch Iporo Abẹokuta on Thursday the 19th day of January-1928.

2. This ceremony was witnessed by a large stream of friends and wellwishers from Lagos Ibadan Ijẹbu and Abẹokuta.

3. It pained me right to the heart for my inability in attending the ceremony of the 19th owing to the nobie call of duty ; but on the 23rd of January I managed one way or the other immediatelly after the service was over to be one of the guests on the table.

4. The Abẹokuta Christian Social Progressive society attended this function on behalf of Mr. I Babat Ṣofoluwẹ, their Secretary for so many years. Refreshments were served to the guests including drinkables and having consumed the delicious dainties set on the table Toasts and speeches followed. Mr. S. B. K. Abiọdun, the native Court Clerk Grade A., was appointed the Chairman and Mr. S. S. Shoyọye " Our lady personified gentlemen " of the assessment's Office acted as the subchairman. The Chairman distinguished himself as a Competent Orater, full of geniality and he captivated the audience very satisfactorily.

5. The following gentlemen were worthy of being mentioned Messrs R. S. Akin Oyebode Headmaster of St. Peter's Ake Abeokuta, Akin Allen, the Controller of the C.M.S. Bookshop Abẹo uta, Roberts, M. S. Shodiya the Senior Assistant Teacher of Ake School, J. S. Ola Fagbemi the Second Assistant Teacher of St. Peter's Ake School P. A. Akinwunmi, the Assistant Teacher of H ly Trinity School Ikereku, J O Akala, T. Ade Ṣofoluwẹ, the Brother of the Bridegroom and the best man of the day, Akin Majọlagbe, the celebrated photographer and a large concourse of friends and family.

6. Many prominent, amiable, loving, " angels " and beautiful ladies appeared on the Table

their gorgeous attire almost in the seven colours of Rainbow to beautify this well attended ceremony.

7. I extend my heartiest congratulation to the society as they survive to pursue freedom from atrocious dealings and being possessors of amenity for this sake I say unto them in the well known Bibilical term "Let Brotherly love continue" wishing the singles to be coupled and the coupled be very happy. After this ceremony a nice grouth of photograph was taken and the guests went to their respective residences.

Thanks for the space allowed.

GEO. S. ADE. LUWAJI LIPEDE

## AYE WA BI?

Bi a ba bere lọwọ ọmọ-ile'we kan pe iṣẹ wo li o fẹ ṣe nigbati o ba jade? Idahun ti a ro pe yio fun wa ko ni ju pe on yio ṣe akọwe lọ. A ko jẹ da irufẹ ọmọ bẹ lẹbi, nitoripe gbogbo wa li a mọ galegale awọn ọmọde lati ṣiṣẹ akọwe, kete ti awọn ba fi Ile'we silẹ, (awa na papa sa ṣe ọmọde ri); Iro inu ọkan wa ni pe, ki iṣe iṣẹ akọwe nikan li o yẹ ki a ma nu ori ọmọde mọ, ogo ati iyi wa pupọ fun pe ki ọmọde kọ iṣẹ kan daju, lẹhin na, bi o ba fẹ, o le lọ dan iṣẹ akọwe wo.

Anfani ti o wa ninu eyi ni pe bi iṣẹ akọwe ko ba wọ fun u mọ, o le lọ fọwọ mu iṣẹ ti o ti ko, ti o si mọ daju larọ rẹ. Anu ṣe ni pe iṣẹ akọwe ṣa fun awọn ọmọ wa yio jẹ idiwọ fun wa lati ko wọn bi a ti nni ẹmi ominira, eyini ni pe, ki a le da iṣẹ silẹ fun ara wa, ibaṣe siso-owọ-pọ lati ma ṣe iṣẹ kan, tabi wiwa ọna miran bi iṣẹ ọwọ (*industry*), tabi owo, ti yio mu wa jẹ eni-ibu-ola-tun lodọ awọn oyinbo. Njẹ, nisisiyi, kili a ri? Bi aye iṣẹ akọwe kan ba ṣeṣi ṣi silẹ ni ibi iṣẹ Ọba (*Government*) tabi ni ile oyinbo oniṣowo ki a to ṣeju-pẹ, ojo iwe (*Application*) ati bọ ṣibi iṣẹ na ti yio rọ si *Office* na ko ni kere: a tilẹ gbọ pe ni ibi iṣẹ miran, a nta ninu awọn akọwe ibẹ ni ipa nigbamiran, ni ohun ti a nri!!! Kili o ro pe o mu eyi wa? Nigbati gbogbo wa ba ṣi bi eṣu si iṣẹ akowe nikan-ṣoṣo lai ronu pe iṣẹ miran mbẹ ti a le fi ri onjẹ ojo wa, ki a si gbọ bukata wa, ogo ni a nfi iwọsi bayi lọ wa? Lati fihan pe iṣẹ akowe ti di ohun ẹgbin, ọpọlọpọ ile awọn oyinbo oniṣowo ni mo ri ni ilu yi, ti nwọn kọ ọrọ wonyi sibi ti gbogbo enia le ri ka ni ile owo won, awon oro na li eyi:—*No vacancy for clerks*, itumọ rẹ ni pe, "Ko si aye fun awon ti o nwa iṣẹ akọwe!!!" Ẹnyin ara, e ko wa ri "imi ẹran ni idi enia" wayi? ni ijọ melo li a ma ṣe eyi gbà? Ni ijọ ti a ba le mu aṣeju a nlọ wa iṣẹ akọwe nikan lati ṣe kuro, nigbana ni a to le bẹrẹ si sọ pe, a nmọ ohun ti a nṣe diẹ-diẹ bi orilẹ-ede.

AJIWOYE.

## CHANGE OF NAME

S. A. COLEMAN-DANIEL

TO

ADENIJI ṢOYỌMBỌ-ABỌWABA.

Commencing from the 1st day of February, 1928, the public are hereby notified that I, formerly known as S. A. Coleman-Daniel, do now desire to be known and called by the name

ADENIJI ṢOYỌMBỌ-ABỌWABA.

All documents bearing my former name remain valid.

## INA WỌ'LE OKUNKUN PARADA.



Atupa ti a npe ni "Oṣupa mi" jẹ oju-lowo ati papin atupa hanun ti o si yẹ ilekile, papa ile awọn gbajumọ olowo, a ko le ṣẹṣẹ ma sọ ti awọn "Dengẹ". Agbara rẹ pẹlu agbara atanpọ ọdunrun abẹla, dede ni, bi ọsan si ni titan rẹ ri ninu ile Agba ti koi ti lowo gbigba Atupa Ṣingo sile ki o ma jafara lati ra atupa meremere yi ti'o na electric jẹ.

Oriṣi meji lo wa fun tita: ti oni-fadaka ati ti onidẹ.

Ẹ lọ yan ti nyin ni Ṣabu Oyinbo KESSLER ni No. 7, Labinjọ Lane.

Ẹnyin ara-oke ati ilu miran, ẹ maṣe gbẹhin ki ẹ to ranṣẹ ti nyin, ki ẹ ma ba j'oku ologbo.

# EKO AKETE

Eko, Saturday, January 28, 1928.

## A DÁ JỌ, A DÁ JỌ, ỌBA NI K' A FA A BAYI !!!

Ọkan ninu awọn ere oṣupa ti awọn ewe ma nṣe leyi nipa pipejọ sibi kan ti nwọn yio si ko aṣọ wọn jọ pọ si ori kan, lẹhin eyi ni ọkan ninu wọn yio bẹrẹ ere na pe "A da jọ, A da jọ", ti awọn ẹgbẹ rẹ toku yio si da lohun pe "Ọba ni k a fa a bayi", ẹnikẹni ti ko ba si tete fa aṣọ tirẹ lẹkanna ti awọn ẹgbẹ rẹ nfa tiwọn, ni nwọn yio pa l'agbọn inu, pa l'agbọn ẹhin nipa fifi gbogbo akojọ aṣọ wọn ju lori; kini ẹkọ ti ere yi kọ ni, ko si ẹkọ meji ju ẹkọ if'ohunṣọkan lọ, bi o ti wa larin awọn ewe, bẹ lo si wa larin agbalagba: iba ṣe ninu ọrọ ile ninu ọrọ adugbo, ninu ọrọ isin, tabi ninu ọrọ ilu; ohun ti o si jẹ alebu fun Eko wa nibi ni pe ipa ni ifọwọṣọkan lati ṣe ohun ribiribi le wa, papa ninu ọrọ ilu.

Lati igbati owo-asingba ko ṣe owo-asingba ti di pipolongo rẹ yi, melo ninu awọn ẹlomiran lo ti lọwọ ninu ajọ ati aisimi aibaye, ti ọpọl pọ awọn ara ilu ti nṣe lati ẹnu bi oṣu mẹjọ sẹhin titi di oni? Nibi ti a gbe nri ti awọn ẹnikan nsa gbogbo ipa wọn lati fi be Ijọba lati kawọ gbigba owo yi ba, ṣe bẹ ni awọn ẹlomiran wa ti nwọn nyinmu, ti nwọn si nyọ ṣuti si ipa sisa awọn alakikanju enia wọnyi; o ṣoro ki nrẹpọ tabi isowọpọ-ṣọkan to le wa fun ọrọ ilu ni Eko nibi, bi ti iru wa, ogiri wa ti pupọ ninu awọn enia ti o mbẹ ninu rẹ jẹ ni, a ko mọ: bi iwa "A donkia fọ dat" ( *I don't care for that* ) si ni o mba awọn ẹlomiran ja ni, awọn papa lo ye: a lai le so ọwọ pọ fun ilọ siwaju ilu lọna òwò ati iṣẹ'lu ninu ki Eko joye ilu "Awa sẹhin ni t' lẹ", a aṣebi iyipada ba wa, nipa nini ilẹ si ohun wọnni ti o le mu ni lọ utẹsiwaju lọna gbogbo.

Tani ọran owo-asingba ti Ijọba npete lati gba yi ko kan? O kan titi o kan awọn ọdọ ati awọn ewe ilu tobẹ ti a fi le wipe ọrọ yi ki ṣ'ọran ẹnikan; ofin gbigba owo-asingba ti di on na, kini ọna ti a o gba lati fi bẹ Ijọba lati ṣi'ju anu rẹ wo ilu lati tẹ gasi ofin na bọ awọ nitori aikuta ti gbogbo "ọja" ti Ijọba "nta" fun wa jẹ, ati papa nitori sisọ fi gbigba owo na lọdọdun le so ilu di ahoro, owo oṣu ẹlomiran ti di h ha bi ẹni ha ẹran Ileya ki oluwarẹ ki o to na wọ gba owo na ni ipari oṣu; pupọ enia ni yio ṣakiyesi pe kilo kuku ṣe ti o fi jẹ pe ọsọsẹ ni a nsọ ti owo-asingba yi, bẹni, ọran lo ba mo ko mo rọ wa, nitori inira rẹ lẹhin-ọla ni a ṣe nlu agogo ra lemọlemọ bẹ.

Lẹkansi, a fi ọrọ orin ti awọn ọmọde ilu l'ọkọrin l'obinrin nkọ lode oni nipa ọrọ yi kọ Ijọba lọrun.

> Maria Mimọ iya Jesu
> Maria Mimọ iya Jesu
> Jọ gbadura fun wa
> Jọ gbadura fun wa
> Nito i owo-ori !!!

---

## ẸGBẸ DẸMỌ KUKO NI YẸYẸ.

[ Wosika lati ọwọ Atari janaku ]

Mo bẹrẹ f'oji

Bi inu ọpọlọpọ enia ti le dun lati gbọ pe Ẹgbẹ Dẹmọ kuro ni yẹyẹ, ẹgbẹ afinju, bẹni a tanma pe a le ri ọgọrọ enia ti inu yio run lati gbọ bẹ. Ẹlomiran ninu wọn, nitoripe nwọn wa ninu ẹgbẹ miran ti o dabi ẹnipe arun sunrun sunrun ( *sleeping sickness* ) kọ lu, ti a s n ṣubu ṣ re si nṣe. Ẹlomiran nbinu Dẹmọ lai ṣe pe o wa ninu ẹgbẹkẹgbẹ kan, bikoṣe pe o nbinu lagbaja tabi tamẹdo to wa ninu rẹ.

A ko le fẹ iro nkan bayi ku rara, eyi lo si yẹ ki o jẹ ayọ nla fun gbogbo ọmọ ẹgbẹ na pe ẹgbẹ Dẹmọ ṣe pataki to bẹ ti a fi nri ẹni a pataki miran ati okumọrata elomiran to nbinu si i. A nju nwọn ko ṣe wi l'ẹjọ, ija ilara ko tan bọr . Ẹ jẹ ki nwọn ma binu nṣọ, abinu ẹni ko le pa kadara da !

Awọn agbalagba yẹyẹ miran ti awọn Hausa npe ni "Soló bansa" nwọn ma kẹgan ngbagbogbo pe awọn talo tile wa ninu Ẹgbẹ Dẹmọ lẹhin awọn Lemọmu ati Marabu pẹlu awọn Kiriyo afi ṣokoto k'ebi s'oke diẹ ?

Ti a ba y'ọwọ awọn Lemomu kuro ati awọn Musulumi ti "Sofó bausa" Marabu, awọn talo tun ku l'Ėko ẹnikeji, ki a ma ṣẹṣẹ sọ ti awọn Onifila funfun, awọn Idẹjọ to ni Ilu to nṣe baba ẹgbẹ na. Laisi ani ani, Imale lo ni Eko, ẹgan ni hẹ. Ẹ ha le ka iye Kiriyo to fi ara kọ si ọdọ Imale ni oniruru ọna, lọ si ibiṣẹ li Apapa, lọ si Okun, lọ si ọgba Reluwe ni Yaba, lọ si Ṣabu Oyinbo papa, lọ si Ebute ẹja lọwọ awọn Alawo, lo si i ikibi, nibiṣe to wa nipo ori to duro fun agbọn mu'ni l'Eko ati nibomiran, tani ao ba nibẹ lẹhin awọn Imale?

Nipaṣẹ awọn Kiriyo ti nwon si npe ni afi ṣokoto k'ebi s'oke to wa ninu ẹgbẹ na, ki a pa ti gbogbo awọn saa i Didi to wa nibẹ ti s'apakan, Aṣoju Igbimo Aṣelu mẹta *Legislative Council* fun Eko, ati Aṣoju mẹta ti Minisipa, ninu ẹgbẹ wo ni nwọn wa bikọṣe Ẹgbẹ ti a nsọrọ rẹ yi? Ẹnikẹni ti o ba si wipe awon Abiọla, Ẹniola, nwọnyi ko to enia, ao fẹ lati mọ baba ti o bi oluwarẹ.

Bẹni nigbati nwọn da Ẹgbẹ *Labour Party* silẹ ni ilu Oyinbo nijosi, bẹni nwọn nyọ ṣuti ete si wọn pe awọn Ilabiru Oyinbo, bantẹ niwaju, iru lẹhin, lo ko ara wọn jọ sibẹ: ṣugbọn loni nkọ, Ọgbẹni Ramsy Macdonald Olori wọn ko ha ti di oriṣi akunlẹ bọ ni ilu Oyinbo loni lori ọrọ Ilu, ko si le ya ẹnikẹni lẹnu to ba nwoye bi nkan ti nlọ si ni ilu Oyinbo nisisiyi lati tun gbọ pe Mr. Macdonald tun di Prime Minister Ajisọba.

Ẹnyin ri ohun to ṣoro da silẹ bi ẹgbẹ titi Anọbi Isa fi pa ipo da l'aiye, ọmọ ẹhin tabi ọmọ ẹgbẹ rẹ ko ju mejila lọ, o ni iba iye ọmọ ẹhin ti Anọbi Muhamọdu fi silẹ l'aiye. Iru enia wo ni awọn ọmọ wọn jẹ, tani ẹ gbọ pe o kọ ile pẹtẹsi bi Ade Oshodi ninu wọn, tani ẹ gbọ pe o mọ gẹgẹ mu to Makọli ninu wọn, tani ẹ gbọ pe rafanda Oyinbo wa l'ori ati l'enu rẹ bi Tomy Jackson ati Ọlọla Dokita Jones ninu wọn, tani Ọlọla bi Lọya Eric O. Moore ninu wọn, Luke tó tilẹ jẹ ọkan ninu awọn Ọmọ nrere to o jẹ Oniṣegun, o ha mọ iṣẹ Oniṣegun ju Ọgbẹni Ṣobi olegbe ati Oniṣegun miran to wa ninu ẹgbẹ Dẹmọ lọ, tabi o gba oye Dokita ti Ọlọla Dokita Caulcrick gba ni ilu Oyinbo

Awọn adẹja *fishermen* ni ọmọ ẹhin Jesu, bẹni a ko si le fẹ adiran ku ninu ti Anọbi Muhamọdu, ṣugbọn loni nko. ọke aimoye enia ko ha njuba wọn. ẹgbẹ tabi ẹsin ti nwọn da silẹ l'aiye ko ha ti di Araba? Bẹ gẹgẹ ni O ngbadura pe ki Ọlọrun ati awọn Anọbi mejì ti a daruko nwọnyi jẹ ki ẹgbẹ Dẹmọ di Araba, ki o di ẹgbẹ ti yio ṣe anfani fun wa ati awọn ọmọ ọmọ wa, pẹlu iran ti nbọ lẹhin.

Ko nṣe ẹgbẹ ti o yẹ ki o fọ rara; nitorina, ni awa ṣe pa fi fi ohun ṣọkan pẹlu awọn alakoso ẹgbẹ na nigbati nwọn wi ninu ọkan ninu ofin wọn pe, iyẹkiyẹ ti ko ba dara mọ ninu ẹgbẹ na, ti tu danu lo yẹ ẹ.

Ipade Ẹgbẹ Dẹmọ ti Satide to kọja lọhun pa banbari. Iwe ẹbẹ nipasẹ ọrọ *Income tax* tabi esu adaiko ti nwọn ka l'ẹgbẹ l'ọjọ na ko si bi o ti ri ni. Fun Ọgbẹni, fun lakaye, fun suru, fun alaye ọrọ, gbogbo rẹ lo pe ṣan ṣan si iwe ẹbẹ na. Rafanda Oyinbo nkọ, a ko le fẹ eyi ku nibiti Makọli, Jakisin, Mọ, Jones, Kolkiiki fi ori k'ori si. Alaga wa bere lọwọ gbogbo Ẹgbẹ pe, ki nwọn fi aṣẹ si iwe ẹbẹ yi lati fi ranṣẹ si awọn enia ati na fọwọ si, ati pe ki a si fi ranṣẹ si Oga awọn Gomina, *(Secretary of State)* ni ilu Oyinbo lati ọwọ Gomina wa, gbogbo ọmọ Ẹgbẹ si na'wọ s'oke patapata pẹlu inu didun. Ọgbẹni Makọli wa la a pe ni Igbimọ ti a ṣe kọja ṣiwaju Ẹgbẹ yi nwọn fi aṣẹ si pe ki a yan enia meji meji ni isọri isọri, awọn Ijoye oni fila funfun meji, Alagbọn meji, Aguda meji, Igbimọ meji, Aṣoju wa ni Igbimọ Aṣofin, Mọ, Jones, ati Kọlkriki. Gbogbo Ẹgbẹ si gba eto na.

Abọ wa ni yi. Ẹni ti o wa si ipade ẹgbẹ Satide jẹ ẹdẹgbẹjọ enia o le mejilelogun.

Emi ni ti nyin nitotọ,
ATARI AJANAKU.

---

## OLUSAKIN'S COLUMN.

### Resumption of Duty.

Venerable T. A. J. Ogunbiyi, Lth., (The Archdeacon of Lagos) and Pastor of St Paul's Church, Breadfruit, Lagos, who has been spending par of his leave at Sapele with Mr. I. T. Palmer and at his farm, Ikeja, returned to Headquarters, on Saturday evening, the 21st instant, and has resumed his pastoral duties as from Sunday the 22nd January, 1928.

### A Medical Practitioner.

Mr. L. R Henshaw, of Calabar, received his M.B., ch B., on December 16, at the University of Edinburgh.

He will probably go through the Tropical School at Liverpool before returning to the Coast.—*West Africa.*

### Installation.

Mr E. M. E. Agbebi, M.A., B.C.L., Barrister-at-Law, was installed on Thursday night, the 17th instant, as Right Worshipful Master of Lodge Scotia, at St. George's Hall.

### Mr. E. A. Ajayi, B.A

There was an "At Home" at 39. Abeokuta Street, Ebute Meta, given by Mr J. A. Odunnade on Friday the 20th January, 1928, in honour of Mr. E. A. Ajayi, B.A., (London).

Among the guests may be mentioned the Right. Rev. Bishop F. Melville & Mrs Jones, H. Carr, Esq., I.S.O., Hon. K. Ajasa, O.B.E., Hon. Dr. C. C. Adeniyi-Jones, E. J. Alex. Taylor, Esq., B.L., Rev. James Pearse, Dr. A. Ovejola A. Alakija, Esq., B.L., Dr. K. Ladipọ Oluwọle, Mr. McEwen, Mr. A. Omodolu, and hosts of others who were kind enough to accept invitations to the Social Gathering.

Mr. Ajayi who is an Ijebu, and was at a time a canoe man and Blacksmith, never attended any University in

England or Sierra Leone, is to be congratulated upon his brilliant success in having graduated B.A., (London) with honours in Philosophy.

## Candid Communications.

OUTSPOKEN MESSAGES TO CELEBRITIES NOTORITIES AND, OCCASIONALLY NONENTITIES.

To Canon F. L. Donaldson, M A.,
Little Cloisters, Westminster Abbey, S W.

Rev. Sir.—As "a Churchman and a citizen" you felt ashamed to stand and preach to miners while hundreds of thousands were half starving and the mind of Church and Parliament was, instead of tackling this great human cry of need, entirely absorbed in Prayer-Book problems. If I read the Gospels aright, I believe the Carpenter of Nazareth would be entirely on your side, and would share both your indignation and your shame.

---

To Admiral Earl Jellicoe, G.C.B., O M.,
Portland Place, W.

My Lord,—Your claim that war brings out the best that is in mankind is one of those half-truths which is more mischievous than a deliberate lie. It is logic at its craziest to suggest that another war, by curing us of our slackness, might prove a blessing in disguise. Many of the evils under which we suffer to-day are the direct legacy of slaughter, and none should know this better than yourself.

---

To the Chairman,
Magisterial Bench, Fleetwood.

Dear Sir,—When Thomas Redman was charged before you with stealing typecases from a steamer, his wife fainted in Court. "You bring her here," you told the prisoner, "in order to impress us, and to try to soften our feelings she faints." Does it not strike you that it is a wife's duty to stick by her man, and that it is impossible to control an anguished heart? However, your bark was worse than your bite, for you let the man off with a fine.—*John Bull* 31/12/27

## Birth.

Madam Comfort Thomas, wife of Mr. Icharius Salakọ Menson, of 61, Taiwo Street, Lagos, was delivered of a female child at Dr. Maja's Dispensary, on Monday morning, the 23rd January, 1928. It is reported that both mother and child are doing well. Congrats.

## Obituary.

The death of Mr. Abudu Lasisi Oke, Carpenter P W D, Ilorin, is announced as having occurred at Ilorin recently.

Mr. Oke was very quiet, kind, social and unassuming.

To his his wife and children, his sister Raliatu Opinke Ogunrẹmi, and to Prince Eman Ọla Okunyẹmiju and all the rest family of the deceased, our sincere condolence *R I.P.*

## Death of Sir Dyce Duckworth.

LONDON.—Sir Dyce Duckworth, an Eminent Physician, died on January 20, 1928 at the age of 87. He was a close friend of late King Edward to whom he was Medical Adviser when Prince of Wales.—*N.D.T.*

OLUSAKIN.

## ORI II.

## IWA—AGBARA TI ẸKỌ ILE NI

*(Translated from "Character by Dr. Smiles")*

APA KẸJỌ.

Ile na le jẹ ibi ti gbogbo anfani ti a n[...] larin awọn ẹbi wa; o le jẹ ile ti a ko [...] gbagbe, nitori ọpọlọpọ ohun idunu ti a m[...] nibẹ; ile bayi a jẹ ibi ọwọ fun ọkan eni[...] ibi isadi ninu iji aiye yi, ibi isinmi ti o [...] ni lara lẹhin lala; itunu nigba ibanujẹ, ib[...] ti a ma ngbe ogun rẹ lori nigba ara ba [...] ni, ati ibi ayọ nigbagbogbo.

Bayi ni a ri i pe ile rere jẹ ile ẹkọ ti o ga ju, ki iṣe nikan ṣugbọn ni agba pẹlu. Nibẹ ni ati ọmọde ati agba nkọ inu rere suru, ikamba ara ẹni ati iwa ifi ara ẹn[...] jẹsin ati imọ iṣẹ ni iṣẹ. Nigbati Izaak Walton nsọrọ nipa iya George Herbert, o[...] ni o jẹ ẹniti o fi ọgbọn tọ awọn ọmọ rẹ, ki[...] iṣe pẹlu ọwọ lile tabi pẹlu ikannu, "ṣugbọn a fi inu didun gba fun wọn ki nwọn ṣere ọmọde ki nwọn si gbadun ara wọn, eyiti o mu awọn ọmọ na fa mọ ọ tobẹ ti nwọn fẹrẹ le ma ya lẹsẹ kan, eyiti o si jẹ didun inu on papa."

Inu ile ni ile-ẹkọ tara nibiti a ma nkọ ọwọ, ẹnikan ko si mọ ni ikọ ni ẹkọ yi to obinrin. Owe awọn French kan ni, "Lais obinrin, abi-iko ni gbogbo enia jẹ". Lati inu ile ni a ti ikọ inure iṣe. Burke ni "Ifẹ ti a ba ni fun ẹlẹgbẹ ẹni ni ipo ti Ọlọrun da wa si, ni iṣe ipilẹ ifẹ ilu."

Oju ko ti awọn ẹniti o jẹ ọlọgbọn julọ ati awon ẹniti o jẹ ẹni rere julo lati sọ p[...] ayọ ati inu didun nlanla ni o jẹ fun wọn lati joko pọ pẹlu awọn ewe ti o njẹ ninu ile wọn.

Ki a ni iwa mimọ, ki a si bojuto iṣẹ ẹn[...] si awọn ara ile ẹni, ara kekere kọ ni eyi ko[...] ninu kikọ enia bi yio ti ṣe iṣẹ ilu; ẹniti o ba si fẹran awọn ara ile rẹ ko ni ṣai ni ife fun ilu rẹ ati lati ṣe iṣẹ fun.

Ṣugbọn bi inu ile ti iṣe ibi ti a kọkọ nkọ iwa ti le jẹ ile-ẹkọ ti o dara ju, bẹ si ni o le jẹ ile-ẹkọ ti o buru ju. Lati igba ewe titi de igba ti a di ọkọnrin, ọṣẹ nlanla wọ[...]

ni iwa aimọkan tabi iwa ope awọn ara ile ẹni ko le ṣe! La i igbati a bi ọmọ silẹ—ti o ke wẹ! wẹ! titi di igbati o mi ẽmi ikẹhin, kini iya ti o jẹ nipa iwa tabi arun, ko ti to eyiti o jẹ ati ọwọ awọn iya ati awọn alabatoju ti ko mọ iṣẹ wọn wa! Gbe ọmọ kan fun oniwakiwa ati ope obinrin ki o tọ ọ, ko si ẹkọ ti iwọ le tun kọ ọ mọ nigbati o ba ti dagba ti o le ṣe atunṣe ibi ti o ti fi ṣe e.

Bi iya kan ba jẹ o'ẹ, oniwakiwa ati ọbun; ti o ba jẹ oniregbe, alawidabọ, alawawi ati ẹniti nkan ko jọ loju, ile rẹ a kun fun oṣi ati ibanuje—ibi ti a sa fun, ki iṣe ibi ti a sa si; awọn ọmọ ti a ba ṣeṣi tọ nibẹ a jẹ oniwa jagbajagba—nwọn a ko oṣi ati ibanujẹ ba ara wọn ati ba awọn ẹlomiran pẹlu.

*Translated By*

ADEYINKA AJAGBE-ỌSA

---

## WOSIKA ỌGBẸNI HERBERT MACAULAY SI AGBẸJỌRO-ỌBA NIPA ỌRAN OWO-ASINGBA.

Gẹgẹbi itara rẹ fun ọro ilu, Ọgbẹni Herbert Macaulay "ro gba" iwe kan l'ede Gẹsi ninu *Daily News* si Agbẹjọro-Ọba, Ọgbẹni D. Kingdon, Oloye M.A., LL.B., Lọya, lati fi aitọ ti o wa ninu pe ki Ijọba funka mọ gbigba owo asingba lọwọ wa: Ọgbẹni Macaulay sọrọ lọ bi i'ẹ bi ẹni lori nkan kanna yi. O si sọ pe nigbati Igbimọ Aṣofin Nigeria gbe ọrọ na soke lati mọ ẹniti o ba fẹ ati ẹniti ko ba fẹ, ki Ijọba nu'ri mọ owo na ni gbigba, a ri pe awọn Oyinbo Oniṣẹ Ọba ti nwọn na'wọ fun gbigba owo na pẹlu Enia Dudu meji ti nwọn gbe awọn Oyinbo wọnyi lẹsẹ, ju awọn ti nwọn ni ki Ijọba maṣe gba lọ; Ọgbẹni Macaulay sọ ti inira nla ti gbigba owo na le mu wa, o si la eyi han Agbẹjọro-Ọba yekeyeke ninu wosika na.

Pi itumọ ṣoki nipa wosika ti ri ni yi o, ẹnyin ẹnia wa.

Ayimọ ki p' ọlọkọ.

---

***Ẹ fi ohun ti iṣe ti Kesari fun Kesari! Ẹ fi ọla fun ẹniti ọla nṣe tirẹ!!***

---

## ORIN NI OHUN ILẸ WA.

---

Ni ẹsẹ keji ohun, Ọgbẹni Karohunwi sọ ọrọ pupọ ti o mu inu wa dun dẹ nipa "Orin ni ohun Ilẹ wa," ṣugbọn bi ọrọ Karohunwi iba ti dara to "ọkọrọ ba ehin aja je," lọna kini nipa pe on ko fẹ lati mọ agba l'ẹgbọn, ati lọna keji nipa pe o gọe ọla ọlọla fun ẹlomiran; nitori eyi, wosika Karohunwi ti ẹsẹ to koja kuna lọpọlọpọ lori alamọri ọrọ ribiribi ti o dunu le.

Awa gbe gbogbo ohun ti Ọgbẹni Karohunwi sọ nipa Prince Ademuyiwa Haastrup (ologbe) ati nipa alufa Ransome-Kuti ti Ijọ C M.S. ni Ake lori alamọri Isin Opopo Ode, ṣugbọn ohun to yanilẹnu julọ nigbati a f'ero lu wosika na ni pe, ohun gbangba kedere wipe Karohunwi "loyun otitọ s'inu ṣugbọn o gbawin ika s'ọrun" ati pe o dabi ẹnpe Karohunwi gbabọdi s'ọkan tabi pe o ni ohun kan pataki ti Karohunwi nfojusọn nipaṣe wosika rẹ na gẹgẹ bi ẹnyin ọkawe wa yo ti ri nisisiyi.

(*a*) Iba ṣe Prince Ademuyiwa Haastrup ni o, tabi Alufa Kuti ni o, ko si ẹnikọkan ninu awọn mejeji wọnyi ti o fi kọ awọn Ijọ wọn pe otun tọ suna to si yẹ fun gbogbo Ijọ enia dudu lati ma ṣe lakoko Isin ninu ile Ọlọrun papa, ni pe ki a ma fi ohun orin ilẹ wa sin Ọlọrun Olodumare nigbagbogbo.

(*b*) Ohun ti awa gbagbọ pe o leke ọkan awọn ẹni mejeji wọnyi ni alamọri ati ma ṣe Isin opopo-ọde lọna ti yio fi mu awọn keferi l'ọkan ti wọn o si wọ inu agbo Igbagbọ. Ayipada ọkan awọn keferi nipa fifi ohun orin ilẹ wa kọrin ninu Isin opopo-ode, eyi ni afokansun awọn mejeji wọnyi, ki iṣe ẹmi ati mu orin kikọ li ohun orin ilẹ wa wo inu Ijọ lakoko Isin ninu Ile Ọlọrun, afi, boya, lakoko Isin pataki nigba kọkan li awọn Ẹlẹgiri iba yọda rẹ.

Ijọ Ibilẹ ati Ijọ Ominira Afrika (eyiti iṣe ojulowo Ijọ orilẹ-ede Enia dudu) mo ni ko si ọkọkan ninu awọn Ijọ mejeji wọnyi ti o nṣe Isin opopo ode nisisiyi! Njẹ bi eyi ba jẹ otitọ, ena wo ni eso iṣẹ Alufa Kuti fi tan de Ijọ Iṣọkan tabi Ijọ Ominira—eyiti iṣe ojulowo Ijọ Orilẹ-ede Enia Dudu? Boya Ọgbẹni Karohunwi (ẹniti nwa awawi nitori ko ba le ri ohun to dun mọ awọn kan leti wi le sọ fun wa!!

Boya o le jẹpe Prince Ademuyiwa Haastrup ati Alufa Kuti lo da aṣa lilo ohun orin Ilẹ wa silẹ fun isin opopo ode ṣugbọn ohun ti awa mọ daju ni pe Dr. Adedeji Ishola ni ẹni na gan ti o kọkọ da aṣa fifi ohun orin Ilẹ wa, Ilu Ilẹ wa, Ijọ Ilẹ wa at-

Ilana Ęsin Ilę wa si Ọlọrun Olodumare ninu Ile-ęsin (Church) ki Ijọ yoku gbogbo to ma gba ara yi da diędię lọwọ rę. Fun ilana rere yi orukọ Dr. Adedeji Ishola yio wa ni iranti fun Orilę Ede Afrika lai ati lailai Amin.

Ọpọlọpọ enia lo mọ otitọ yi ti wọn si njęri si nigbagbogbo, ibaşe larin Ilu Eko yi tabi lęhin odi, Ipinu ti awọn Ijọ Ọmọ Ibilę gbarajọ şe ni ọdun 1922 nipa (Pastor now) Bishop Adedeji Ishọla, D.M., D.D., tun jęri si otitọ ọrọ yi pęlu; Ipinu na niyi l'ede Oyinbo:—

**Resolution moved and passed at the Anniversary Public Meeting held on Tuesday, September 12, 1922, at Jehovah Shalom Church, Lagos, at 7 p.m.**

---

Resolution: 2. That this Organization records its high appreciation and heart-felt thanks, towards the Brotherhood Christian Church, of which Pastor A. Adedeji Ișọla, is the Founder and Superintendent, which has kindly consented to allow its Drum and Drummers to assist in, and thereby enhance the celebration of this our 31st Anniversary, in a manner very much pleasing to the Church.

That this Organization believes that the time has come for the introduction in all the African Churches, of such native songs, native musics, and native Drums into our Divine Services, and for this purpose urges that efforts should be directed to examine, gather, compose, arrange, and to use those native songs, native musics, and native Drums which are harmonious to the Christian religious services, and that these be systematically taught and encouraged in this Organization, for the worship and praise of our blessed Lord and Master, Jesus Christ.

*Moved by* Revd. E. A. Akiọla, *and seconded by* Revd. G. A. Oke.

Mo rope ęnyin ọkawe wa yio ri gbangba nisisiyi wipe Ọgbęni Karohunwi kuna lọpọlọpọ ninu wosika rę ti ọsę to kọja nitoripe ko fę fi ohun ti işe ti Kesari fun Kesari, bęni ko si fi Ọla fun ęniti Ọla nşe tirę, kakabę nşe lo fi aiyederu ta Ọla Ọlọla fun ęlomiran; "a ha le binu ori titi ka fi fila de idi?" Ba le ni, ba ba ni, iwọn la ba ni ș'ọta mọ.

ALAFIYESI.

---

## A CORRECTION.

We are glad to report that what we published in good faith in our last issue realative to the raging of an alleged Epidemic at Ode Ondo, as vouchsafed to us, turns out to be the outcome of misinformation.

[ED. E.A.]

# OWO-ORI.

---

## EȘU NPETE ATI LA, AKOWO ĘBỌ KO NI JĘ.

Owo ori, Owo ile, Owo omi, Owo dukia, ati orișiriși ọna ti a fi ngba owo lọwọ wa; o ję aşa ti o șe ajeji fun enia dudu ni ilę Yoruba; ohun gbogbo ti a ka s'oke wọnyi ti wọn si ngba ni ilu Eko ati ni ilu Oke loni ję nkan bi "Akowaba," nitoripe enia dudu ko lo da silę, șugbọn awọn alabagbe wọn lo kan nipa fun Ijọba enia dudu lati ma gba owo yi lowọ gbogbo awọn ti nwọn njọba le loni, ki wọn le ri owo lati pin fun wọn losoșu ati lati fi iyoku ba wọn tun ilu wọn șe dara-dara.

Ni ilu Oke șaju Ijọba oyinbo gbogbo wọn lo nsin ęru, nwọn a si ma jagun pęlu lati mu enia l'ęru, ki wọn le ri ęni ti yio ma roko fun wọn ati lati șișę miran, bi lati ręru ati lati ma ranșę.

Ko si owo, bęni wọn ko si mọ ohun ti o nję "Owo Ori" titi o fi di akoko ti awọn Aguda de ilu Eko, ti wọn ko "Ọti Agba," "Ewe Taba," Așọ Aran oriși-riși, Ętu ibọn, Iyọ, ati nkan miran ni awọn ara igbani nma gba dipo ęru, o si ję pașiparọ larin awọn mejeji, iru ipo bayi ni awọn Yoruba Eko pęlu awọn oyinbo gbogbo igbani wa pęlu ara wọn nigbati owo ęru bęrę.

Nigbati o șe awọn Aguda wa mu Owo Ęyọ, iru eyi ti nwọn nná ni ilu Așia, ti wọn si ma nwa ninu omi erekușu kan ni Phillipines, ni apa ila Orun wa si Eko, nigbati wọn ri pe a ko ni owo l'Eko lati ma na, awọn lo kọkọ ję ki a mọ ohun ti o nję owo pęlu awọn Payan (Spanish) ati awọn Gęsi miran ni ilu Amęrika gbogbo wọn li o nwa ko Ęru ni ilu wa ni ọpọkuyọku ti wọn si nko wọn lọ da si Oko ireke. Lati igbana ni Owo Ęyọ ti bęrę si tan kakiri ni ilę Yoruba, o si wa ni ilu Oke, ni Ọyọ ati ni Ilesha titi di oni oloni.

Oyinbo lo lę ki a mọ ohun ti wọn nfi owo șe, ohunkohun ti won ba si pe ni owo fun wa ni a nna, owo na lo si di pașan, eyi ti a nfi na wa nisisiyi.

Nigbati wọn ko awọn enia wa lọ si ilu Aguda ati ilu Payan, nibę ni wọn sọ fun wọn iye ti owo ori wọn ję ti wọn ni lati san ki wọn to di ominira nipa abọșę ti wọn nșe, wọn nfi owo dię dię pamọ titi pupọ ninu won le san owo ti wọn da fun wọn lati san eyi ni "Owo Ori" wọn.

Nigbati owo-ęyọ de Eko ati ilu Oke, nigbana ni awọn Ara Oke ndiyele ęru ti wọn ba fę ta, nigbana ni Ęru papa mọ owo ti o wa lori on, ati lati igbana lọ ni ęru ti mọ ara rę ni Olowo lori, ati pe wọn ni lati san Owo Ori wọn ki wọn to le ra ara wọn. Ni iru ipo ișę bayi ni enia dudu ti ilu Aguda ati ti ilę Yoruba wa fun ọdun pupọ, nigbati o ma fi to bi iwọn igba ọdun sęhin (1760 A.D.) Awọn Aguda ti ko bi iwọn ọkę meje enia ni ęru lọ

si ilu Jamaika nikanşoşo ni akoko Ijọba Obinrin (Queen Llizabeth 1558—1603.)

Awọn kan ti wọn da Ẹsin Ifẹ kan silẹ ti wọn npe ni Quaker ni ede Oyinbo, awọn lo kọkọ gbe ọrọ Ẹru dide ni ilu Oyinbo ti wọn si nla bi ko ti tọ fun ẹda lati ma lo ẹda ẹgbẹ rẹ ni ilo-kulo. ani bi ẹni lo Ẹranko igbẹ. Lẹhin na Ọgbẹni Thomas Clarkson ẹniti o kọ iwe pataki lori si sin ẹru, ati Ọgbẹni Granville Sharp ẹniti o joko l'ori Aga lati pana Owo ẹru, ati William Wilberforce ẹniti o sọrọ ni apejọ nla ni ile awọn Onilu ati awọn Ọjọgbọn (The House of Parliament) pe ki Ijọba ko pẹlu wọn, ati pe ko şe iranlọwọ fun won lati da awọn ẹru silẹ, ati Ọgbẹni kan ti o niẹ Zachary Macauley, Baba Lord Macauley gbogbo won lo dide ni ilu Oyinbo pẹlu iranlọwọ Ọlọrun ti wọn si pana Owo ati Ẹru ni ilu Oyinbo ati Aguda titi di oni.

Nigbati o di ọdun 1807. Ọgọfa ọdun sẹhin, nigbati George III wa lori oye ni ilu Gẹsi; nigbana ni wọn şe ofin ti wọn fi da owo ẹru duro, ati niwọn ọdun mọkanlelọgbọn lẹhin na, wọn da gbogbo ẹru ti o wa ni gbogbo ilu Oyinbo silẹ eyi ti o jẹ ẹgbẹgbẹrun lọnọ ẹgbẹrin. 800,000, ni 1st Augnst 1838, iyẹn ni gbogbo ilu ti o wa ni abẹ Asia Gẹsi gbogbo won lo di ẹni omnira ara wọn pupọ pada si ilu wọn, pupọ ninu won si ti ku, awọn ọmọ won ko mọ ọna ile tabi ilu iya ati baba wọn mọ, awọn na lo fi ibẹ şe ile titi di oni.

Owo tian tian, ọkẹ aimoye ni owo ti Ijọba Gẹsi san fun awọn Oluwa Ẹru wọnyi (£2,0000,000) ki a to da wọn silẹ.

Lẹhin na awọn ti nwon wa ni isalẹ Amẹrika kọ lati da awọn ẹru tiwọn silẹ. Ijọba Gẹsi ni lati gbe Ogun tiwọn, wọn si şẹgun wọn; ni ọdun kẹtalelọgọta 1863) l hun ni gbogbo ẹru di omnira patapata, ati igbana lọ ni awọn Aguda ti bẹrẹ si pada si ilu Eko diẹ diẹ.

Awọn Ijoba Gesi şe fun enia dudu pupọ, awọn lo fi wa si ipo adi Kọla, ati awọ Yẹri, ati awọ bata loni, bi ko ba şe tiwọn ni Loya pupọ ni ibati ku si Oko-ireke tabi ki ibadi awọn Olowo kofi şe—wuruku bi awọn Mọmọyin ati Papayi ti wọn kọkọ de si Eko, ni aiye igbani ti wọn si nma bẹrẹ ki wọn to le rin fun on ti oju wọn iba ri. Ni ọdun 1861 ni Ijọba Gẹsi de si Eko, wọn si şe adehun pẹlu Ọba Akitoye I pe ko da owo ẹru duro nitori nigbati Aguda ko ra ẹru mọ awọn Eko wa gba işẹ na si ori, wọn si sọ owo Ẹru di owo pataki ni ilu yi, nitorina ni awọn ti wọn npe ara wọn ni ẹni pataki l'Eko loni lo şe jẹ pe ọmọ ẹru ni wọn nşe. Ijọba Gẹsi ni ki a ma sin ẹru mọ, o sọ gbogbo ẹru di omnira, awọn ẹru ko san owo ibọkun l'ori ara wọn mọ, gbogbo yi lo dun mọ wa ninu.

Kini tun mu Ijọba Gẹsi kana ti wọn ni ki a tun ma san owo ori, tabi Ijọba Gẹsi ti lailai yatọ si ti isisiyi, tabi owo ti Ijọba (Qeen Victoria) san le wa lori ni o nbi awọn Ijọba akoko yi ninu ti nwọn si nfẹ lati gba pada lọwọ wa, eyi ko ye wa o. Lati igba ti Gẹsi ti de si Eko, a ko ni Oluwa meji, awọn na ni a nsin titi di oni, nigbati nwọn sọ wa di omnira tan, ti wọn lo Akata jina tan, nigbana ni wọn tun pada wa mu Adie; nwon ni ki a ma wa san owo ori—fun kini o, awa ko mọ o, nitori wọn ko gbọdọ so pe owo ti nwọn ri gba l'Eko ko to nna, a si nri ki pe on nşẹku fi ọdọdun.

Wọn ha nfẹ lati sọ wa di ẹru lẹrinkeji ni, ti o ba jẹ bẹ ki wọn kuku so iye owo ti onikaluku ni lati san, bi o ti jẹ pe wọn ko tẹ ki nkan tun şe ẹnu re fun wa mọ yẹn—Bi ẹnikan ba le dagba to iwọn ọgọrin ọdun, ti Ijọba ba yo mẹrindinlogun kuro ninu rẹ, ti o si ku mẹrinlelọg ta ẹni bẹ ni lati san pọun mejilelọgbọn. (£32) ki o to ku fun owo ori iyẹn ti jẹ o ẹnyin ara wa ti ẹ nyọ lọrun-lọrun bi ako pẹpẹyẹ fun owo ori ni sisan, ẹ ko ro ti ẹhin ọla fun awọn fun awọn ọmọ yin ati awọn arugbo pẹlu, awọn baba wa ko ma ba aiye tiwa jẹ c, bi ẹ ba si ba ti awọn ti ọmọ yin jẹ, o ku si ọwọ yin o, nitori epe şọrọ ni wọn o ma rojo lẹ ori Sare yin fun iru imra ti ẹ fi silẹ fun wọn," Orişa bi o ko le la mi ko şe mi bi o ti ba mi" bi a ko ba le tun şe fun wọn, a ko gbọdọ fi silẹ bi a ti ba?

Ijọba nfẹ lati tokun bọ wa l'ọrun, lati fi ọgbọu sọ wa di ẹru totọ, a si tun ngba erupẹ ti Ijọba lẹsẹ lati şe iranlọwọ fun u, pẹlu gbogbo iwe, ogbon ati lakaiye yin, ko si jẹ pe nitotọ iru l'oku ka di Ọbọ.

Ẹyin Ijọba a bẹ yin o, ẹ ma tun sọ wa di ẹru mọ o, ẹnyin lẹ ni ki a ma tun sin ẹru mọ o, ẹnyin na ki ẹ ma si fi ọgbọn sọ wa di ẹru, nitori owo ori ki nşe ti ọmọ l'uwabi bi ko şe ti ẹru, gbogbo wa lo mọ ara wa ni ẹru oyinbo ẹ si ti fi owo ori wa jin wa, ẹ ma tun mu wa san owo ori mọ o—Oyinbo lailai ke npurọ—a ko mọ ti akoko yi o, Eşu npete ati la o, şugbọn ẹyin a kowo ẹbọ ẹ ko majẹ o. Ọran yi ti gbogbo ilu ni o ẹ jọwọ, ẹ gbawa o.

JALANKATO.

---

## Obituary.

### JAMES O. HOTONU

### 31, Offin Road, Lagos.

**YESTERDAY.**

## White's Golden Male Tonic

DOUBLE STRENGTH).

Whenver a woman has not been in the family way for a long time, the fault is usually set down to some disease or other in her generative organs.

Now while it is true that many women suffer from disease, yet many times the fault lies with the man, owing to weakness or some other disease of the male organs of generation. White's Golden Male Tonic (Double-Strength) is calculated to give full vigour to the man, and to remove all diseases which prevent breeding. Every sensible man ought to use two bottles every month, to cure or prevent weakness of the generative organs.

Made and sold only by VICTOR WHITE, Esq., *The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos.*
*N.B.*—NOT OBTAINABLE ELSEWHERE.
"Shake the Bottle."

AREMO FUN OKUNRIN.

Nigbati obinrin ko ba tete loyun, a ma nro pe ara obinrin na nikan ni arun wa. Şugbọn nigba pupọ ni o nię pe ara ọkunrin ni arun wa. Egbogi yi dara pupọ fun Arę, Ęda ati gbogbo arun ti ki ę ki ọkunrin şe abiamọ.

*N.B.*—O yę ki gbogbo ọkunrin ma lo igo meji-meji loşoşu—Işę ti egbogi na nşe ni ara ko şe royin.

Price TEN SHILLINGS (10s) per bottle.

*Postage 2/6 extra.*

## White's Golden Female Tonic.

A splended Remedy for Female diseases such as:—Barrenness, Weakness, Painfull and Irregular, Menstruation Leucorrhœa (Whites) Cramps, Ovarian, Neuralgia, Inflammation of the Ovaries. A Tendency to Miscarriage etc, etc.

Made and sold only by VICTOR WHITE Esq.
41, Offin Road, Lagos.
*N.B :– Not obtainable elsewhere.*

GBOGBONIŞE FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun Al oyun, Iju, Ęda, Aran, Oyun ti o ba fę baję, ati orişirişi arun mi ti ki ję ki obinrin bimọ.

PRICE 10/- PER BOTTLE.
Postage 2/6 extra.

WHITE'S
## WONDERFUL BRAIN TONIC

This medicine stimulates and rebuilds the brain in such a way, that the regular user is able to do many times the usual amount of Brainwork that he used to do, before using it. To Brainworkers and those who have examinations to pass, it is a boon.

Made and sold only by SAMUEL VICTOR WHITE, Esq
41, OFFIN ROAD, LAGOS.

Large size 5/- per bottle. Packing and Postage 2/6 extra.
Small size. 2/6 per bottle. Packing and Postage 1/6 extra.
N.B.—*Scholars should not be without it.*

EGBOGI ISỌYE.

Egbogi yi dara pupọ fun awọn ọmọ-ile-iwe, awọn ti o nfi iwe şişę ati gbogbo awọn ti o ba ni lati lọ fun idanwo.

*Iba şe ọmọde tabi agbalagba.*

## White's Golden Blood Restorer

*(A Native preparation for Women.)*

This medicine is an excellent remedy for Insufficiency or Loss of the monthly courses, Tumour in the Womb, False Pregnancy, Catarrh of the Womb, Various Runnings or Morbid Discharges from the Womb (especially those that are long-standing).

Sick Headaches, Dizziness, etc., etc.

Made and sold only by
VICTOR WHITE, ESQ., *Chemist,*
The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos

"SHAKE THE BOTTLE".

Price TEN SHILLINGS (10/-) per bottle.

*Packing and Postage 2/6 extra, to any part of Nigeria.*

EGBOGI ILANA ĘJĘ FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun obinrin ti ko ba ri nkan oşu rę mọ (lalai to aseko), nkan obinrin ti ko ba pọ to. Aşę Ewurę pipọju, Ęda ti o ba gbo, Ęyo, Oyun-koyun. Oyun ti ko ba dagba, Oyi, Ęsanri ni akoko hela, Aran ati Iju.

## HORSFIELD'S

The well known suppliers of all classes of goods under the registered Trade "ZODIAC" Mark.

Call and see our Agent and give your orders to:—

MR. MOSES O. COKER,

Port Novo Market Street, Lagos.

who has samples every mail of all the latest styles of fancy and other goods, including our REGISTERED Palm Tree and Feather Embroideries.

We supply everything.

J. J. HORSFIELD & CO.,
( Manchester ) Limited,
65, George Street,
Manchester.

## GOOD MARKET.

Gonorrhea Specific, Moloke Mone, A. & D. Bula Matadi for health-restoring purposes: these Medicines are on sale at Mr. H. Campos's First Class Shop. 37, Odunlami Street, Lagos. The Specifie acts like Magic: has cured many obstinate cases, and *will cure yours just the same*, if any.

Cheap Goods! Superior Quality!! Quick Fortune!!!

*Cable Address*:—"WHITE LAGOS".

MR J. T. AKIREMI WHITE
P.O. Box 82
20, Balogun & Breadfruit Streets
or
41, Offin Road, Lagos.

**Indents House.**

Import of General Lines
Export of Produce Commission Agencies undetaken.

Correspondence invited.

With over 22 years' experience in this line of business.

Mr. White's well-known connexion with reliable Firms in Europe is a matter of common knowledge to his clients.

A Trial is Solicited.


When replying advertisers please mention *Eko Akete*


## TO LET.

One Splendid Pleasure Car

No. L2754.

***Always at everybody's service at Tinubu Square.***

For Terms, Apply to:—

A. B. Williams,
14, Bishop Street, Lagos.

## *ILE OWO OYINBO*

# JOHN RADCLIFFE

Ni No. 63, Ehingbeti, Eko.

—— :o: ——

Ile-owo ti o wuyi fun ọja meremere bi Ṣẹda, aṣọ Yọm[illegible]
ati aṣọ ti a fi ẹlẹya Oyinbo gbaleti.

Ẹ wa bẹ orişirişi ọja wa wo ni Ile-owo wa titun to k[illegible]
si Ile Niger ni No. 63, Ẹhingbẹti.

Aşọ lorişirişi ni aşetejọ: aşọ Ṣẹda ati Siliki mbẹ bi a[illegible]
awọn wọnyi jẹ eyiti awọn onibara ṣa ti nwọn si ti sami si [illegible]
ra wọn. Aşọ lami-titi ti a npe ni Ṣantọnu nkọlu 'ra wọn.

Agbalẹtu ni gbogbo ọja wa fun didara wọn

Pọ ọ si ni owo wọn.

PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING PRESS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED B[illegible]
ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.